# IFẸ ỌLỌRUN

**1 Kọrinti 13:1-13**

**ẸKỌ 355 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Nisisiyi igbagbọ́, ireti, ati ifẹ mbẹ, awọn mẹta yi: ṣugbọn eyiti o tobi jù ninu wọn ni ifẹ” (1 Kọrinti 13:13).**

## Ifẹ

“Ifẹ ni Ọlọrun; ẹniti o ba si ngbé inu ifẹ o ngbé inu Ọlọrun, ati Ọlọrun ninu rẹ̀.” Awọn eniyan Ọlọrun ni ifẹ Rẹ̀ ninu ọkàn wọn nitori pe Ọlọrun wà ninu wọn Nigba ti awọn eniyan ba ri igbala, a o dari ẹṣẹ wọn ji, Ọlọrun a si fi ifẹ Rẹ̀ sinu wọn. Nigba ti a ba sọ wọn di mimọ́, a wẹ ọkàn wọn mọ́ wọn si ni ifẹ Ọlọrun lọpọlọpọ ninu ọkàn wọn. Awọn ti o ba ri igbala nikan ni o n ni ifẹ Onigbagbọ́ tootọ, nitori pe awọn Tirẹ̀ ni Ọlọrun pese rẹ̀ silẹ fun.

Ifẹ ti Ọlorun ma n fi sinu ọkan awọn eniyan Rẹ̀ ni a n pè ni ifẹ Onigbagbọ́ ati ifẹ ará. Ifẹ yii jinlẹ ju fifi owo fun awọn talaka lọ. Ifẹ yii jẹ́ itara fun anfaani, itura, ati inu didun awọn ẹlomiran. Iṣesi ati ibakẹdun wa si awọn ẹlomiran ni o n fi ifẹ hàn.

## Bi ifẹ ti ṣe Pataki to

Fifẹran awọn eniyan Ọlọrun jẹ ọna kan lati fi hàn pe Tirẹ̀ ni wá. Jesu wi pe: “Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mọ̀ pe, ọmọ-ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nigbati ẹnyin ba ni ifẹ si ọmọnikeji nyin” (Johannu 13:35). Ninu iwe ti Peteru kọ a kà a pe, “Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ẹ ni ifẹ ti o gbóna larin ara nyin” (1 Peteru 4:8). Leke ohun gbogbo! Ifẹ ni a kọkọ darukọ ninu akojọpọ awọn ohun amuyẹ ti o papọ di “eso ti Ẹmi” (Galatia 5:22). A pe Ifẹ ni “ohun ti o tobi julọ ninu ayé.”

## Odiwọn

Paulu kọwe si awọn ara Kọrinti nipa ifẹ Onigbagbọ́, eyi ti ó pè ni “ifẹ”. Apá Iwe Mimọ yii jẹ́ iwe lori ifẹ. On ni odiwọn ti a le fi wọn igbesi-ayé wa gẹgẹ bi Onigbagbọ́. Bi a ti n kọ́ ẹ̀kọ́ yii, ẹ jẹ́ ki a gbé igbesi-ayé wa le ori ọpa idiwọn yii ki Ọlọrun ba le fi ọna ti a maa fi jẹ́ Onigbagbọ́ ti o jafafa si Oluwa hàn wá. Ibikibi ti o wù ki wọn maa gbé, ẹnikẹni to wù ki wọn jẹ́, bi o ti wù ki wọn kere tabi ki wọn dagba tó, gbogbo Onigbagbọ́ ni o ni awọn ohun amuyẹ wọnyii nitori pe ifẹ Ọlọrun wà ni igbesi-ayé wọn.

## Alainifẹ

Paulu ṣe ifiwera laaarin ifẹ ati awọn ohun rere miiran. Ọpọlọpọ eniyan ni o ni itara lati le sọ ède ẹlomiran; ṣugbọn gbogbo eniyan ni o le gbọ́ ède ifẹ ti a fihàn nipa ẹrin músẹ́, ẹmi ibanikẹdun, ati nipa awọn iṣẹ inu rere miiran.

Ọpọ eniyan ni o n fẹ olohùn iyọ̀. Mose mọ̀ wi pe oun ki i ṣe olohùn iyọ̀. Nigba ti Ọlọrun pe e lati mú awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti, Mose wi pe, “Emi ki i ṣe ẹni ọ̀rọ-sisọ … ṣugbọn olohùn wuwo ni mi, ati alahọn wuwo” (Ẹksodu 4:10). Ṣugbọn Ọlọrun sọ fun Mose pe Oun yoo kọ́ọ ni ohun ti yoo wi. O maa n dùn mọ ni nigba ti eniyan ba sọ̀rọ̀ pẹlu ohùn-iyọ̀, ṣugbọn ki i ṣe nini ohùn-iyọ̀ ni o ṣe pataki julọ. Paulu fi ohùn-iyọ̀ ti kò ni ifẹ wé iro asán ti “idẹ ti ndún, tabi bi kimbali olohùn goro” (1 Kọrinti 13:1).

Paulu ni oun kò jamọ nnkan kan bi oun kò ba ni ifẹ; ani bi oun ba tilẹ le sọ asọtẹlẹ awọn ohun ti n bọwa ṣẹ lọjọ iwaju; bi oun ba tilẹ ni oye gbogbo ohun ijinlẹ Ọlọrun; bi o ba tilẹ jẹ pe oun ni imọ ati ẹ̀kọ́ lati inu iwe kika ati lati ọdọ awọn olukọ; ani bi oun tilẹ ni igbagbọ́ lati fi ṣi oke nidii. Ṣugbọn ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn awọn eniyan Rẹ̀ tobi ju gbogbo wọnyii lọ.

Awọn ẹlomiran lawọ́. Wọn a maa fifun awọn akúṣẹ ati alaini. Awọn miiran ṣolootọ tobẹẹ ti wọn le yọọda pe ki a fi wọn rubọ. Ṣugbọn laisi ifẹ ti Ọlọrun, awọn nnkan wọnyii kò le mu ère kan ti o niyelori wa. Awọn ẹbun ti Paulu darukọ wọnyii dara nitootọ, ṣugbọn wọn kò tó. Eniyan gbọdọ ni ifẹ Ọlọrun.

## Suuru ati Inurere

“Ifẹ a mã mu suru.” Ifẹ Ọlọrun a maa fun eniyan ni suuru. Jobu ni suuru nitori pe o jẹ eniyan Ọlọrun. Nigba ti Jobu padanu awọn ọmọ ati awọn ohun ini rẹ̀ o wi pe: “Oluwa fifunni Oluwa si gbà lọ, ibukun li orukọ Oluwa” (Jobu 1:21). Nigba ti ipọnju rẹ̀ pọ̀ si i, o fara mọ eyikeyi ti Ọlọrun ṣe. O wi pe: “Ṣugbọn on mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀, nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura. Ẹsẹ mi ti tẹle ipasẹ irin rẹ̀, ọ̀na rẹ̀ ni mo ti kiyesi, ti nkò si yà kuro” (Jobu 23:10, 11). Iwọ ha n mú suuru nigba ti o dabi ẹnipe ohun gbogbo diju? Boya ohun ti o kù ọ́ kò ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ, lati fun ọ ni suuru, tabi ohun ti o kù fun ọ ni lati dagba ninu suuru ati ifẹ Ọlọrun.

"Ifẹ … a si mã ṣeun." A kà a ninu awọn iwe Paulu si awọn ara Efesu pe, "Ẹ mã ṣore fun ọmọnikeji nyin" (Efesu 4:32). Josẹfu jẹ apẹẹrẹ rere ẹni ti o n ṣoore paapaa si awọn ti o ti huwa iwọsi si i. Awọn arakunrin Josẹfu korira rẹ, wọn si ta a fun awọn oniṣowo, awọn ẹni ti o mu u lọ si Egipti; ṣugbọn ni akoko iyàn, Josẹfu mu awọn arakunrin rẹ wà laaye nipa fifun wọn li ounjẹ. O wi fun wọn pe, "Njẹ nisisiyi, ẹ má bẹru: emi o bọ́ nyin, ati awọn ọmọ wẹrẹ nyin." "O si tù wọn ninu, o si sọ̀rọ rere fun wọn" (Gẹnesisi 50:21). Ta ni iwọ n ṣore fun? Si kiki awọn ti n ṣe ọ lore nikan?

**Nirẹlẹ**

Ifẹ Ọlọrun maa n jẹ ki eniyan ni itẹlọrun dipo ilara. A sọ funni pe ki ohun ti a ni "ki o to" wa (Heberu 13:5). A kà a pe, "Iwa-bi-Ọlọrun pẹlu itẹlọrùn ère nla ni" (1 Timoteu 6:6). Awọn onilara a maa kùn si ohun rere ti awọn ẹlomiran ni. Kò si ohun rere kan ti a le sọ nipa ilara. A le ri akọsilẹ awọn eniyan ti o kún fun ilara ninu Iwe Mimọ́, akọsilẹ kọọkan ni o kún fun ibanujẹ. Kaini pa arakunrin rẹ nitori ilara. Awọn ẹni ti o fi ẹsún kan Daniẹli ti a fi sọ ọ́ sinu iho kiniun ṣe e nitori ilara. Awọn olùfisun Kristi yọọda pe ki a kan An mọ́ agbelebu nitori ilara.

Ifẹ maa n mú ki eniyan rẹ ara rẹ silẹ dipo ifẹ̀-sokè. A kọ́ wa ni iwa irẹlẹ ninu Ọrọ Ọlọrun. Kà nipa rirẹ ara-ẹni silẹ ninu Iwe Owe 22:4; Jakọbu 4:10; 1 Peteru-5:5, 6. Ọkan ninu awọn ohun ti Ọlọrun n fẹ lọwọ wa ni pe ki a "rin ni irẹlẹ" pẹlu Rẹ (Mika 6:8).

**Aimọ-ti-ara-ẹni-nikan**

"Ifẹ … ki ihuwa aitọ́." Njẹ iwa ti o tọ́ ni lati maa yọ eniyan lẹnu; tabi lati maa yọṣùti si eniyan nigba ti o ba kọ̀ lati ṣe ohun ti a n fẹ fun wa bi? Awọn ọmọ miiran a maa binu lainidi nigba ti nnkan kò ba lọ bi wọn ti n fẹ́, wọn maa n mu wahala bá awọn ẹlomiran titi nnkan ti wọn n fẹ́ yoo fi tó wọn lọwọ. Ṣugbọn iru awọn ọmọ bẹẹ kò ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wọn.

"Ki iwá ohun ti ara rẹ̀". Ifẹ ṣe alainimọ-ti-ara-ẹni-nikan tobẹẹ ti ki iwá ohun ti ara rẹ̀. Wo bi o ṣe yatọ si ẹmi ti ayé, eyi ti o n mu ki awọn eniyan maa nọga si ohun gbogbo, yala wọn ni ẹ̀tọ́ si i tabi ti ẹlomiran tilẹ ni! Ayọ̀ tootọ kò si ninu gbigbà bikọṣe ninu fifunni. "Ẹ si mã ranti ọ̀rọ Jesu Oluwa, bi on tikararẹ̀ ti wipe, Ati funni o ni ibukun jù ati gbà lọ" (Iṣe Awọn Apọsteli 20:35).

**Ọkàn Titun**

"Ifẹ….a ki imu u binu." Wo ogunlọgọ eniyan ti wọn ti gbidanwo lasan lati le kapa ibinu wọn! Nigba ti a ba mu wọn binu, wọn a ti sọ̀rọ wọn a si ti ṣe ohun ti wọǹ yoo pada kabamọ fún. Inufufu a maa yọrisi ibinu, ikorira ati igbẹsan. Nigba ti eniyan ba binu, ki i sọ ọ̀rọ̀ rere bẹẹ ni ki i lè huwa ti o dara. Kò si ipá ti a le sà lati le kapa ibinu, bi ko ṣe ki a mú orisun wahala yii – ti i ṣe ọkàn – wá si titọ́. Ifẹ Ọlọrun ni o maa n fi iranwọ sinu ọkàn ti a ki i fi mu u binu.

"Ifẹ.....ki igbiro ohun buburu." Onigbagbọ́ ki i lànà ibi ki i si ṣaṣaro lori ibi. Ki i ni ifura si ẹlomiran, lati maa woye fun ibi ni igbesi-ayé wọn. Filippi 4:8 fun wa ni akojọ awọn ohun rere ti o yẹ ki a maa ronu nipa rẹ: awọn ohun ti iṣe ootọ, ti iṣe ọ̀wọ, ti iṣe titọ́, ti iṣe mimọ́, ti iṣe fifẹ, ti o ni irohin rere: "bi iwa-titọ́ kan ba wà, bi iyin kan ba si wà, ẹ mã gbà nkan wọnyi rò."

**Ni Ifarada**

"Ifẹ ki iyẹ̀ lai." O ni ifarada. Awọn nnkan miiran yoo kuna, yoo rekọja, tabi yoo fi àyè fun ohun titun. Igbagbọ́, ireti ati ifẹ mbẹ nisisiyii -- ṣugbọn ni Ọrun kò ni si lilo igbagbọ́ ati ireti. Ifẹ nikan ni yoo wà titi. Nipa awọn ohun mẹta wọnyii Paulu wi pe, "Eyiti o tobi jù ninu wọn ni ifẹ." Igbagbọ́ ati ireti jẹ ohun ti o ṣe pataki ni igbesi-aye Onigbagbọ́. Ni aisi igbagbọ́ o ṣoro lati wu Ọlọrun (Heberu 11:6). Igbagbọ́ ni iṣẹgun ti o ṣẹgun ayé (1 Johannu 5:4). A sọ fun wa pe ki a "jà gidigidi fun igbagbọ́, ti a ti fi le awọn enia mimọ lọwọ lẹkanṣoṣo" (Juda 3). Ireti jẹ́ apakan ninu ihamọra Onigbagbọ́ -- "ireti, igbala fun aṣibori" (1 Tẹssalonika 5:8). Ireti ni "idakọ̀ro ọkàn, ireti ti o daju ti o si duro ṣinṣin" (Heberu 6:19). Igbagbọ́ ni iwa wa si Ọlọrun. Ireti wà fun awa tikarawa. Ṣugbọn ifẹ tobi ju awọn wọnyii lọ. Ifẹ Ọlọrun ni ohun ti o n mú ki a fẹran aladugbo wa.

Gẹgẹ bi o ti n kọ́ ẹ̀kọ́ yii gbé igbesi-ayé Igbagbọ́ rẹ le ori ọpa-iwọn, njẹ àyè wà fun itẹsiwaju? Ranti pe n ṣe ni Onigbagbọ́ n dagba si i, a si maa pọ̀ si i ninu oore-ọfẹ kọọkan ti Onigbagbọ́. Peteru wi pe ki a ṣe aisimi gbogbo ati pe ki a fi kún awọn ohun amuyẹ wọnyii: igbagbọ́, iwa-rere, imọ̀, airekọja, suuru, iwa-bi-Ọlọrun, ifẹ ọmọnikeji ati ifẹ. Nipa idagba Onigbagbọ́ a o ni anfaani lati so eso ti ẹmi ati lati sọ "ipe ati yiyàn" wa "di dajudaju," ati lati wà pẹlu Jesu ninu Ijọba Rẹ̀ ainipẹkun. Ṣugbọn bi a ba kùnà ninu awọn nnkan wọnyii a o kuna iye ainipẹkun. (Ka 2 Peteru 1:5-11).

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni orukọ miiran ti a tun le pe ifẹ?

2 Bawo ni eniyan ṣe le ni ifẹ?

3 Ifẹ Ọlọrun ti ṣe pataki tó?

4 Ki ni a ṣe le mọ ẹni ti o ni ifẹ Ọlorun?

5 Ka ninu 1 Johannu 4:19 idi rẹ̀ ti a fi fẹran Oluwa?

6 Bawo ni awọn eniyan ṣe le mọ̀ pé ọmọlẹyin Jesu ni wá? Jesu kọ́ wa pe ki o ma ṣe kiki awọn aladugbo wa nikan ni a o fẹran ṣugbọn bẹẹ gẹgẹ ki a tun fẹ awọn ta ni?

7 Ki ni ohun ti o ṣẹlẹ bi Onigbagbọ́ kò ba dagba?

8 Ninu ẹsẹ ti o kẹyin ninu ori ẹkọ wa, a fi ye ni pe ifẹ tobi ju awọn ohun meji miiran wo ni ó wà?